# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## ỌLỌ̀TẸ̀ ỌMỌ-ỌBA ỌKÙNRIN

## Ìtàn ...

**2 Samuel 13:1-8, 33**

Absalomu jẹ́ arẹwà ọkunrin, ti o wuni ati ẹni ti o ni ìpinnu ọkan laarin awọn ọmọ baba rẹ́, Dafidi. Bibeli wípé, "Kò sí arẹwà kan ni gbogbo Israeli tí a bá yìn bi Absalomu: lati atẹlẹsẹ rẹ̀ títí de àtàrí rẹ̀ kò sí àbùkù kan lara rẹ̀." 2 Samueli 14:25.

Ọdọmọde-kunrin ọmọ-ọba tó ní ìpinnu yí tún fẹ́ jù ìyìn ti awọn eniyan nfun un nitori ẹwà rẹ̀ lọ. Ó fẹ́ agbara ìtẹ́ bàbá rẹ̀. Ó fẹ́ lati di ọba Israeli - lọnakọna. Ní àkọ́kọ́, Absalomu pa ẹ̀gbọ́n rẹ̀ Amnoni, lẹ́hìn ti Amnoni ti ṣe àbúrò rẹ̀ Tamari bi kò ṣe fẹ́. Amnoni jẹ́ àkọ́bí ọmọ Dafidi ti o yẹ lati jẹ ọba lẹhin Dafidi. Lẹ́hìn ìgbàtí Absalomu ti wá ojúrere bàbá rẹ̀, ó bẹ̀rẹ̀ si ilo ọgbọ́n lati gbin èso iyèmejì si ọkàn awọn eniyan niti ìjọba bàbá rẹ̀ ni gbogbo ẹkùn ìjọba náà, niti ìdájọ́, ati niti òfin títí ó fi "fa ọkàn awọn eniyan Israeli sọ́dọ̀ rẹ̀." 2 Samueli 15:6.



Lakọtán, ìpinnu ibi rẹ̀ wá di nlá, èyítí kò ṣe fi ọwọ́ bò mọ́, títí tí Absalomu si fi di ọlọ̀tẹ̀ ti o fẹ lati pa bàbá rẹ̀, ki ó sì jí ìjọba gbà lọ́wọ́ rẹ̀. Ṣùgbọ́n lẹhin ogun ọjọ́ melokan, a tún fi ìdí Dafidi kalẹ̀ padà sí orí ìtẹ́ rẹ̀, a si pa Absalom, arẹwà ọmọ ọba ọkùnrin náà.

Èyí jẹ́ ìtàn tó bani nínújẹ́, ṣùgbọ́n ki iṣe ìgbà àkọ́kọ́ ti ọmọ-ọba ti ma nkópa nninú rúkè-rúdò. Ní ìjọba nlá kan ni àkókò kan sẹhìn, irú ìṣẹ̀lẹ̀ bayi náà sẹlẹ̀, ti o sì fẹ́rẹ̀ jẹ́ ọ̀tẹ̀ tó tún nsẹlẹ̀ ni ìgbà gbogbo.

Ìjọba náà ni a npè ni - ọ̀run!

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọọkan tán.

1. Kíni orúkọ ọlọ̀tẹ̀ ọmọ-ọba ọkùnrin náà lí ọ̀run, kílọ́ dé to fi ṣọ̀tẹ̀?

**Isaiah 14:12**
Báwo ni iwọ ti ṣe ṣubú lati ọ̀run wá, Iwọ __________, ìràwọ̀ òwúrọ̀! bàwo li a ti ṣe ké ọ lu ilẹ̀, iwọ ti o ti ṣẹ́ awọn orilẹ-èdè li apá!

**Isaiah 14:13,14**
Nítorí iwọ ti wí li ________ rẹ pé, Emi o gòkè lọ sí ọ̀run, emi o gbe ìtẹ́ mi ga kọjá ìràwọ̀ Ọlọrun: emi o si joko lórí òkè ijọ eniyan ni ihà àriwá: Emi o gòkè kọjá gíga awọsanma: emi o dabi __________ ________.

**Esekieli 28:17**
Ọkàn rẹ gbe sókè nítorí _________ rẹ, o ti ba ọgbọ́n rẹ jẹ́ nítorí ________ rẹ; emi o bì ọ lulẹ̀, emi o gbe ọ kalẹ níwajú awọn ọba, ki nwọn ba le wò ọ́.

Àkíyèsí: Lusiferi jẹ́ ọ̀kan pàtàkì ninu awọn ẹ̀dá ỌLọrun, tí ó sì ni ẹwà púpọ̀. Ó jẹ́ ọ̀kan lára awọn olórí ninu awọn angẹli ati ẹniti ó ma ndarí awọn akọrin ní ọ̀run. Ṣùgbọ́n, ó gbà kí ẹwà rẹ̀ kósi i lórí debi ti ó fi gberaga. (Wo àfikún "Ọba Tire ati Babiloni tí wọn dúró fún Satani")

2. Njẹ́ Ọlọrun dá èṣù nígbàtí Ó dá Lusiferi bí?

**Esekieli 28:15**
Iwọ _______ li ọ̀nà rẹ lati ọjọ́ tí a ti dá ọ, títí a fi ri __________ ninú rẹ.

Àkíyèsí: Ọlọrun dá angẹli pípé, ẹniti ó wá yàn lati di èṣù funrarẹ̀. A le ma gbàgbọ́, ṣùgbọ́n bí ó bá ṣe wípé a ní ànfààní lati mọ̀ Lusiferi kí ó tó subú ni, a o fẹ́ràn rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wípé a o mọ̀ bí o ti ṣe pẹ́ tó, o le jẹ́ pé Lusiferi ti sin Ọlọrun fún ìgbà pípẹ́ kí ó tó di ìgbàtí ó nfẹ́ gberaga títí ti o fi dàgbà li ọkàn rẹ̀. Oluwa ìbá ti dá awọn ẹ̀dá Rẹ̀ ni ọ̀nà ti wọn yio fi ni agbara lati sisẹ́ bí i akúra ti a npè ni "robot", ṣùgbọ́n robot kò le è ni ìfẹ́. ìfẹ́ tòótọ́ gbọdọ̀ ṣetán lati fi ara da ewu. Ìdí nìyí ti awọn èniyàn fi yàn lati má a bi ọmọ, nitori wọn mọ̀ wípé, awọn ọmọ náà le è yàn lati ṣe àìgbọràn bó bá wù wọ́n. Ọlọrun fi Lusiferi silẹ̀ lati wu ìwà ọ̀tẹ̀ rẹ̀ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí. Ní àkọ́kọ́, lati yanjú ìbéèrè yi pé, bóyá Ọlọrun dá awọn ẹ̀dá Rẹ̀ lati yàn ohun tó bá wù wọn àbí bẹ́ẹ̀ kọ́. Èèkejì, bí Ọlọrun bá pa Lusiferi run ní kété ti ó ti ntan ìròhìn búburú èyí tó mú kí àwọn eniyan má a siyèmejì lórí ìfẹ́ ati ìdájọ́ Ọlọrun, ọ̀pọ̀ awọn ẹ̀dá Ọlọrun miran tí wọ́n jẹ́ ọlọ́gbọ́n ni wọn ó tún má béèrè ìbéèrè nígbà gbogbo. Wọn le è rò pé, "Lusiferi jẹ́ olótítọ́." Nítori náà ni a ṣe fi Lusiferi sílẹ̀ lati ṣe àfihàn ìwà búburú rẹ̀ tí iṣe abayọrí ẹ̀ṣẹ̀. Li àkótán, Ọlọrun kò fẹ́ ki àwọn ènìyàn Rẹ̀ má a gbọ́ràn sí Oun lẹnu nítori ìbẹ̀rù ìyà ti yio fi jẹ wọn bi wọn kò bá gbọ́ràn. Ọlọrun nfẹ́ ki awọn eniyan Rẹ̀ má a gbọ́ràn si Oun nínú ìfẹ́, ki iṣe nínú ìbẹ̀rù.

3. Kíló sẹlẹ̀ ni ìgbẹ̀hìn?

**Ifihan 12:7**
__________ si mbẹ li __________: Mikaeli ati awọn angẹli rẹ̀ nbá dragoni naa jagun; dragoni si jagun ati awọn angẹli rẹ̀.

Àkíyèsí: Ní ìgbẹ̀hìn a lé Lusiferi àti awọn angẹli tí wọ́n pẹ̀lú rẹ̀ jáde kúró ni ọ̀run.



4. Awọn alágbara wo ló nsiṣẹ́ labẹ àṣẹ èṣù?

**Ifihan 12:4**
Ìrù rẹ̀ sì wọ__________awọn ìràwọ̀, o sì ju wọn si ilẹ ayé, dragoni naa si dúró níwájú obinrin náà tí ó fẹ́ bímọ, pé nígbàtí ó bá bí, kí ó le pa ọmọ rẹ̀ jẹ.

**Ifihan 12:9**
A sì lé dragoni nlá náà jáde, ejò lailai ni, ti a npè ní Èṣù, ati Satani, ti ntàn gbogbo ayé jẹ, a si lé e si ilẹ ayé, a si le awọn __________ rẹ̀ jade pẹlu rẹ̀.

Àkíyèsí: Àrékérekè Satani pọ̀ tó bẹ́ẹ̀, ti ó fi lo ẹ̀tàn lati tan ìdámẹta àwọn angẹli ọ̀run lati sọ̀tẹ̀ sí Ọlọrun. Níbayi, a pè é ni "èṣù" ati "demoni," àwọn angẹli tí wọn subú wọ̀nyí ni wọn mú ìpinnu Satani ṣẹ. Ninú ìtàn Absalomu ti a nsọ, a ri wípé ó ṣe díẹ̀ ninu iṣẹ́ ìdọ̀tí rẹ̀. Absalomu pàṣẹ fun àwọn ìránṣẹ́ rẹ̀ lati mu ìfẹ́ rẹ̀ ṣẹ.

**2 Samueli 13:28**
Absalomu si fi aṣẹ fun awọn ìránṣẹ́ rẹ̀ pé, Ki ẹnyin ki o ma kiyesi àkókò ti ọtí-waini yio mu ọkàn Amnoni dùn, emi o si wí fun nyin pé, Kọlu Amnoni; ki ẹ sì pa á: ẹ má bẹ̀rù: ṣe emi li o fi aṣẹ fun nyin? ẹ ṣe gírí, ki ẹ se bi alagbara ọmọ.

**2 Samueli 14:30**
O si wí fun awọn ìránṣẹ rẹ̀ pé, Wò ó, oko Joabu gbè ti emi, o si ni ọkà níbẹ̀; ẹ lọ ki ẹ sì tinábọ ọ. Awọn ìránṣẹ́ Absalomu sì tinábọ oko náà.

5. Ọ̀nà wo li Satani ma ngbà ṣe iṣẹ́ rẹ̀?

A. **Ifihan 12:9** - A sì lé dragoni nlá náà jade, ejò lailai nì, ti a npè ni Èṣù, ati Satani, ti __________ gbogbo ayé jẹ, a si lé e jù sí ilẹ̀ ayé, a si le awọn angẹli rẹ̀ jade pẹlu rẹ̀.

B. **Marku 1:13** - Ó sì wà li ogojì ọjọ́ ni ijù, a ti ọwọ́ Satani __________ an wò, o sì wà pẹlu awọn ẹranko ìgbẹ́; awọn angẹli si nṣe ìrànṣẹ́ fun un.

D. **Ifihan 16:14** - Nítorí ẹ̀mí èṣù ni wọn, ti nṣe __________, nwọn ti ẹnu dragoni naa ati ẹnu ẹranko naa ati ẹnu woli èké náà jade wá.

E. **Ifihan 12:10** - Mo sì gbọ́ ohùn rara li ọ̀run, nwipe, Nígbayi ni ìgbàlà dé, ati agbara, ati ijọba Ọlọrun wa, ati ọla ti Kristi rẹ̀; nitori a ti lé _________ awọn arakunrin wa jade, ti o nfi wọn sùn níwajú Ọlọrun wa lọsán ati loru.

Ẹ. **Johannu 8:44** - Ti èṣù baba nyin li ẹnyin iṣe, ifẹkufẹ baba nyin li ẹ si nfẹ ṣe. __________ li oun iṣe lati àtètèkọṣe, kò sì dúró ninu òtítọ́; nítorí tí kò si òtítọ́ ninu rẹ̀. Nigbàtí o ba nṣeke, ninu ohun tirẹ̀ li o nsọ, nítorí èké ni, ati baba èké.

Àkíyèsí: Ní ọ̀nà kan, Satani ni ànfààní ju Ọlọrun lọ ninu ìjà tó wà laarin rere ati búburú. Ọlọrun ma nlo òtítọ́ nìkan, ṣùgbọ́n Satani le è lo òtítọ́ tàbí irọ́ lọ́nà to bá wù ú, lati mu ipinnu ọkàn rẹ̀ ṣẹ. (Wo àkórí yi ninu àfikún "Ìrètí lori ohun ti a kò retí.")

6. Ní ikorita wo ni èṣù ti jẹ́ elewu jù?

**2 Korinti 11:14,15**
Ki si iṣe ohun ìyanu; nítorí Satani tikararẹ̀ npa ara rẹ̀ dà di __________ __________, Nítorí naa ki iṣe ohun nla bi awọn ìránṣẹ rẹ̀ pẹlu ba pa ara wọn dà bi awọn ìranṣẹ òdodo; ìgbẹ̀hìn awọn ẹniti yio ri gẹ́gẹ́ bi iṣẹ wọn.

Àkíyèsí: Gẹ́gẹ́ bi èṣù ti ṣe, Absalomu náà ṣe bi ẹniti o fẹràn awọn eniyan, ó sì fi ara hàn bi ẹnipe ìlera awọn eniyan náà kan oun ṣùgbọ́n ọ̀nà lati tàn wọn jẹ ni.



YOR-SP4.indd 1 12/6/12 10:23 AM

**2 Samueli 15:5,6**
Bẹ̀ẹ̀ni bi ẹnikan ba si sunmọ ọn lati tẹriba fun un, oun a sì nawọ́ rẹ̀, a si di i mú, a sì fi ẹnu kò ó li ẹnu, Irú ìwà bayi ni Absalomu a ma hù sí gbogbo Israeli ti o tọ̀ ọba wá nítorí idajọ: Absalomu si fa ọkàn awọn eniyan Israeli sọ́dọ̀ rẹ̀.

7. Njẹ́ Satani mọ̀ Bibeli bí?
**Matteu 4:5,6**
Nígbà naa ni Èṣù gbé e lọ sókè si ìlú mímọ́ nì, o gbé e le ṣónṣó tẹmpili, O sì wí fun un pé, Bi iwọ ba iṣe Ọmọ Ọlọrun, bẹ́ sílẹ̀ fun ara rẹ: A sá ti _______ rẹ̀ pé, Yio paṣẹ fun awọn angẹli rẹ̀ nitori rẹ: li ọwọ́ wọn ni nwọn o si gbé ọ sókè, ki iwọ ki o má ba fi ẹsẹ̀ rẹ gbún òkúta.

Àkíyèsí: Èṣù ma ntúmọ̀ ó sì tún ma n si Bibeli túmọ̀ lati tan awọn eniyan jẹ. Èyí lo fi ṣe pàtàkì fun awọn ènìyàn Ọlọrun lati mọ Ìwé-Mímọ́ funrara wọn, ki a má ba sì wọn darí.

8. Tani Satani korira jù lórí ilẹ̀-ayé?
**Ifihan 12:17**
Dragoni náà sì bínú gidigidi sí _________ náà, o sì lọ bá awọn irú-ọmọ rẹ̀ ìyókù jagun, ti nwọn npa òfin Ọlọrun mọ́, ti nwọn si di ẹ̀rí Jesu Kristi mú.

9. Irú ẹranko meji wo li Bibeli lò lati ṣe àpèjuwe Satani?
**1 Peteru 5:8**
Ẹ maa wà li airekọja, ẹ maa ṣọ́ra; nítori èṣù, ọ̀tá nyin, bi ________ ti nké ramuramu, o nrìn kaakiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri.
**Ifihan 12:9**
A sì lé dragoni nlá náà jáde, _________ lailai ni, ti a npè ní Èṣù, ati Satani, ti ntàn gbogbo ayé jẹ, a si lé e si ilẹ ayé, a si le awọn angẹli rẹ̀ jade pẹlu rẹ̀.

Àkíyèsí: Kiniun ati ejò ma nṣápamọ́ si ìkọ̀kọ̀ ati pé wọn ma ngba onírúurú ọ̀nà lati mu ounjẹ wọn. Bẹ̀ẹ̀ náà li èṣù, ẹniti o jẹ alai-ní-àànú ti kò si le bani dárò, ti ó sì déédé ma nru sókè níunú ayé awọn ondè rẹ̀.

10. Ọ̀nà kan soso wo ni a fi le è gbógun ti Satani?
**Jakọbu 4:7,8**
Nítorí náà ẹ _________ fun Ọlọrun. Ẹ kọ ojú ìjà sí Èṣù, oun ó sì sá kúrò lọdọ nyin, Ẹ _________ Ọlọrun, oun o sì sunmọ́ nyin, Ẹ wẹ ọwọ́ nyin mọ́, ẹnyin ẹlẹ́ṣẹ̀; ẹ si ṣe ọkàn nyin ni mímọ́, ẹnyin oníyè méjì.

Àkíyèsí: Àwọn ọ̀nà tó dára jù lati súnmọ́ Ọlọrun ni inú àdúrà ati pé ki a má a gbìyànjú lati mọ̀ Ọ́n sí i nípa ọ̀rọ̀ Rẹ̀.

11. Báwo ni Jesu ṣe sẹ́ ogun èṣù?
**Matteu 4:10**
Nígbà náà ni Jesu wí fun un pé, Padà kúrò lẹhin mi, Satani: nitori a _________ rẹ̀ pé, Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki ìwọ ki o forbalẹ̀ fun, oun nìkan ṣoṣo ni ki iwọ maa sìn.
**Efesu 6:17**
Kí ẹ sì mu aṣiborí ìgbàlà, àti idà Ẹmí, ti iṣe ________ ________.
**Heberu 4:12**
Nítorí _______ Ọlọrun yè, o si li agbára, o sì mú ju idàkʼídà olójú meji lọ, o sì ngúnni àní títí dé pípín ọkàn ati ẹmi níyà, ati orike ati ọ̀rá inu egungun, oun si ni olùmọ̀ èrò inú ati ète ọkàn.



Àkíyèsí: Ọ̀nà àbáyọ kan ṣoṣo tí a fi le yọ ninu ẹ̀tàn Satani ni wípé ki a ma pa ọ̀rọ̀ Ọlọrun mọ́ ni ọkàn wa lati mu wa sá fun ẹ̀ṣẹ̀. Ohun ìjà yi kan-náà ni Jesu lò lati fi jʼagun pẹ̀lú èṣù, ni àwa náà nilò ati wípé wọn wà nílẹ̀ fun wa loni.
**Orin Dafidi 119:11**
Ọ̀rọ̀ rẹ ni mo pamọ́ li àyà mi, ki emi ki o ma ba ṣẹ̀ si ọ.
**Efesu 6:11**
Ẹ gbé gbogbo ìhámọra Ọlọrun wọ̀, kí ẹnyin ki o le kọ ojú ìjà si àrékérekè Èṣù.

12. Báwo ni abajade ìwà Satani ṣe jọ ti Absalomu?
**2 Samueli 18:17**
Nwọn sì gbé Absalomu, nwọn sì sọ ọ́ sínú _______ nlá kan ni igbogan náà, nwọn sì papọ̀ òkúta púpọ̀ jọ si i lórí, gbogbo Israeli sì sá, olukuluku sí inú àgọ́ rẹ̀.
**Isaiah 14:15**
Ṣùgbọ́n a o mu ọ sọ̀kalẹ̀ sí ipò òkú, sí ihà _______.

13. Ṣe Satani yio má a farahàn títí lati má a dán awọn ènìyàn Ọlọrun wò ni?
**Esekieli 28:19**
Gbogbo awọn ti o mọ̀ ọ laarin awọn orilẹ-èdè li ẹnu o yà sí ọ: iwọ o jẹ ẹ̀rù, iwọ ki yio sì _______ mọ́ lailai.
**Nahumu 1:9**
Kíli ẹnyin ngbìrò sí OLUWA? oun o ṣe ìparun dé òpin, ìpọ́njú kì yio dìde _________.

14. Báwo ni pípa àwọn eniyan búburú ṣe rí lara Ọlọrun?
**Esekieli 33:11**
Sọ fún wọn pé, Bí emi ti wà, ni Oluwa ỌLỌRUN wí, emi kò ni _________ ni ikú eniyan búburú, ṣùgbọ́n ki eniyan búburú _________ kúrò nínú ọ̀nà búburú rẹ̀ ki o sì _______: ẹ yípadà, ẹ yípadà kúrò ninú ọ̀nà búburú nyin; nitori kini ẹnyin o ṣe kú, Ilé Israeli?

15. Báwo ni Dafidi ti ṣe nígbàtí ó gbọ wípé a ti pa ọlọ̀tẹ̀ ọmọkunrin rẹ̀ Absalomu?
**2 Samueli 18:33**
Ọba sì _________ púpọ̀, ó sì gòkè lọ sí ìyẹ̀wù tí ó wà lórí òkè bodè, ó sì sọkún; bayi li o sì nwí bí ó ti nlọ, ọmọ mi Absalomu, ọmọ mi Absalomu! aa! ìbáṣepé emi li o _________ ní _________ _________, Absalomu ọmọ mi, ọmọ mi.

# Èsì Rẹ

Àwòrán yi nfi yé wa bi Baba wa ọrun ṣe ma nṣe nípa awọn ọmọ Rẹ̀ tó sonù. Ki iṣe wípé Ó fẹ́ ku ni ipò wa nìkan; Ó tún tẹ́síwájú ni ìgbésẹ̀ kan si i - Ó fun wa ni ẹ̀bùn Rẹ̀ tó ga jù, Ọmọ Rẹ̀! Ọlọrun kò fẹ́ ki ẹnikẹni ṣègbé. Ó fẹ́ ki o di ẹni ìgbàlà. Ìdí nìyí ti Jesu fi kú ni ipò rẹ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú ayé ni wọn ti darapọ̀ mọ́ Satani ni sísọ̀tẹ̀ si Baba ọrun. Ṣe o fẹ́ yàn lati fẹ́ràn ati lati ma a sìn In?

ÌDÁHÙN: _____________



# Àfikún

Ipele yi pèsè ìròhìn lati kẹ́kọ̀ọ́ tẹ́síwájú.

## A lo Ọba Tire ati Babiloni lati dúró fun Satani

Nínú Isaiah 14:4-15, Bibeli lo ọba Babiloni gẹ́gẹ́ bi àmì Satani, ati ninu Esekieli 28:11-19, Satani dúró fun ọba Tire. Nínú ẹsẹ mejeejì, a mọ̀ wípé àmì náà kọjá ti ọba ayé nítorí pé apàjúwe Ọlọrun nípa ẹ̀dá náà kò le è jẹ́ ti eniyàn kíkún lásán. Wo ọ̀nà ti a fi júwe Lusiferi (ti a npè ni Èṣù níbayi) ninu awọn ẹsẹ wọ̀nyí:

- ò subú lati ọ̀run (Isaiah 14:12)
- ó kún fun ọgbọ́n, ó sì pé ni ẹwà (Esekieli 28:12)
- ó ti wà ni Edeni (Esekieli 28:13)
- òkútà iyebíye gbogbo ni a fi bò ó (Esekieli 28:13)
- oun ni kerubu ti a nà ti o sì bò (Esekieli 28:14)
- ó wà lórí òkè mímọ́ Ọlọrun (Esekieli 28:14)
- ó pé li ọ̀nà rẹ̀ (Esekieli 28:15)

Níwọ̀n ìgbàtí àwọn ọba Babiloni ati ti Tire ti fi ìlànà kan-nàn hàn ati wípé wọn yio jọ jẹ ìyà ìparun kàn-nàn gẹ́gẹ́ bi i ti ìjọba Satani, Ọlọrun wá lò wọ́n lati dúró fun Satani gan-an-gan. Ó fẹ̀rẹ̀ jẹ́ wípé gbogbo àṣẹ Bibeli ni wọn sowọ́pọ̀ lórí àmì náà. Ní ọ̀nà kan tàbí òmíràn, Bibeli ṣe àkójọ àwọn ẹsẹ lati tọ́ka si Lusiferi (Wo Luku 4:5,6; 10:18; Johannu 8:44; 2 Peteru 2:4; 1 Johannu 3:8; Juda 6; Ifihan 12:7-9), ṣùgbọ́n láìsí Esekieli ẹ̀i ati Isaiah ẹ̀é, a kò ní ní ìtàn pípé.

## Ríreti ohun ti a kò rò tẹ́lẹ̀

Ọ̀pọ̀ ènìyàn ló fẹ́ kí Satani yọjú ni gbangba gẹ́gẹ́ bi ọ̀tá Ọlọrun ni àkókò ìkẹhìn yi, ṣùgbọ́n èyí kò ri bẹ́ẹ̀. Nígbàtí, Satani jẹ́ ọ̀tá Ọlọrun tó burújù, ṣùgbọ́n ọ̀nà tí yio gbà wá yio jẹ ọ̀nà ẹ̀tàn ti yio ṣe bi i olododo (Matteu 24:24). Ó le è farahàn gẹ́gẹ́ bi i ẹni ògo tàbí ì angẹli (2 Korinti 11:13-15) kí ó sì ma á wá ki àwọn ènìyàn jọ́sìn si oun (Ifihan 13:12). Ìwé-Mímọ́ fi ye wa pé, ìwà rere rẹ̀ yio pọ̀ gidigidi tí yio sì yí àwọn eniyan lọ́kàn padà títí tí "gbogbo ayé" si fi tẹ̀lé ẹranko náà (Ifihan 13:13). Sọ̀rọ̀ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ búburú kan! Satani yio ṣe àṣeyege ninu ẹ̀tàn rẹ̀ pé oun ni Kristi dé ibi wípé gbogbo ayé ni yio tẹle, tí wọn yio sì má a rò nígbà gbogbo pé, àwọn ntẹ̀le Jesu. Ṣé a o tàn ọ jẹ bí? Ki iṣe ọ̀rọ̀ bi o bá fẹ́ gba ìkìlọ̀ Bibeli ni a sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ ninu àwọn ẹ̀kọ́ wọ̀nyí.

## Angẹli tí ọpọlọ rẹ̀ pé pérépéré

Inú Satani ma ndùn nígbàtí àwọn ènìyàn bá júwe rẹ̀ bi i òbùrẹ́wà, oniyẹ-àdán tí a dá ni apá kan ènìyàn ati apá kan ẹranko, tó tún yà bàtà-ẹsẹ̀, ati pé ó ní ìrù gígùn ati wípé ó ma nbu èédú sí iná ọrun apadi. Kò si ohun ti a le è fi tẹsiwaju nínú òtítọ́ náà. Irú àwọn ìtàn agbori-rò yi wá láti inú ìtàn tó ti pẹ́, ti o nsàlàyé lori àwọn ohun ti ẹmí ti iṣe ti Griki (ni èdè òyinbo "Greek mythology"). Láílái, a kò le rí irú rádaràda bí èyí ninu Ìwé Mímọ́ rárá. Bibeli júwe pé Satani jẹ́ ẹnití ọpọlọ rẹ̀ pé pérépéré, ati angẹli ti ó rẹwà pẹ̀lú agbara àjèjí lati ba ènìyàn sọ̀rọ̀. Ó tún mọ Ìwé-Mímọ́ dáradára (Matteu 4:5,6). Èṣù jẹ ẹni ti o ma npolongo ara rẹ̀ bi ọ̀tá Ọlọrun, ti ìpinnu rẹ̀ sì jẹ́ lati ba sọ̀rọ̀ òdì lati ba ìwà Ọlọrun jẹ́ ati pé ki o tún gba ìjọba Rẹ̀. Satani ma ngan ìwọ ati àwọn olólùfẹ́ rẹ, ó sì tún pinnu lati ọ run. Àwọn ẹ̀kọ́ yi, yio ràn ọ́ lọ́wọ́ lati ni òye ìpinnu èṣu ati ọ̀nà ti o ó gbà lati ba ìpinnu rẹ̀ jẹ́ ki o má ba ṣẹ. Ìwọ sá ti fi ayé rẹ̀ sí abẹ́ ààbò Olùgbàlà rẹ nlá, ki ó sì gbàdúrà gidigidi fún ìtọni Rẹ̀.

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP4.indd 2 12/6/12 10:23 AM